# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. IV. No. 171. SATURDAY, OCTOBER 24, 1925. 4d

***The People's Leading Vernacular Paper.***

N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.
OYINBO **J. F. SICK**
Ọba Ilẹkẹ, Ile Ilẹkẹ, 9, Ita 'Bode lailai, Eko

A jẹ Ajirera ninu òwò Ilẹkẹ, orişirisi Ilẹkẹ wọnyi wa ni tita :—

Ilẹkẹ Oyinbo, Ilẹkẹ Rubber, Ilẹkẹ Olomi Wajì, Ilẹkẹ Onikẹkẹ, Ilẹkẹ Elejo, Ilẹkẹ Ayinrin, Ilẹkẹ Oniwõrò ati Fadaka, Ilẹkẹ Kerewu, Ilẹkẹ Jòjò, Ilẹkẹ Ölokuta, Ilẹkẹ Oloruka, Ilẹkẹ Ẹlẹranko, Ilẹkẹ Didan Yinrinyinrin, Ilẹkẹ Meremere, Ilẹkẹ Mọjọkun, Ilẹkẹ Adumãdan

Ẹ wa wo Ile ọja wa ; A ni nkan wọnyi fun tita :—

Ikoko Taba Onigi, Jigi, Aşọ Aran, Ẹrọ Agbado, Ife, Ọti Elewuro (*Beer*) ati Eleso Ajèrà (*Wine*), Awọn Onjẹ Ipanu, Aşọ Iş'ọşọ, Ero Ere Ọmọde, Ohun Ọşọ, Abẹla (*Candles*) ati ẹgbagbeje oja miran.

A nta Masini *Vesta*, a si ni *Cement* atata ti Portland ati Irin pipọn abẹ oni *Diamond*. Idi òwò wa wa ni Rotterdam, a si ni Ile Owo ni :— Calabar, Gablonz (Czecko-Slovakia) Gold Coast, Accra, Lome Hamburg, London, Venice (Italy).

***Electric Novelties.***

Mr. M. SADIKU has assorted kinds of Electric Materials, 2 & 3 lights, Brackets, Shades, etc, too numerous to mention.

He undertakes the contract of wiring houses at very reasonable prices.

And has also in stock louder bells complete with wire and Salamomical ready for connections. Call at 18 Ọbun Eko Street, Lagos, for your selection.

*P.O. Box 378.*

**WHO SAYS TOOLS?**

Ọgbẹni J. O. BANKỌLE ti Daddy Alaja *Street, Lagos*, ni wabiwọsi irin işẹ *Carpenter*, fun tita, awọn irinşẹ bĩ Kọkọrọ, *Rachet Braces*, *Coffin Handles*, *Wall Papers*, ati bẹbẹ lọ. Ọpọku ọyọku ni owo wọn.

Jòjò nyaju ni wọn.

# OPEN AGAIN

## AND IN

## FULL SWING

# LEVER

# STORE

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Offices*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

ONINI BABA EWU.

Ọgbẹni D. L. Oshodi ti 36, Idoluwo *Street, Lagos* ni oriṣiriṣi *Ivory Coat & Trouser Button* (Onini) fun tita kósi aṣọ ti ko ni *button* to yẹ. O si ni wabi-wọsi ero-ija *Tailor* (*Tailors Trimmings*) ni tita bakanna; o si nfa'ṣọ ṣe *button* (*Press Coat Buttons*) ki awọn af'aṣọ-dara (*Expert Tailors*) maṣe jafara lati ba ra tiwọn; ọpọku-ọyọku ni ọja meremere wọnyi.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

P. ST. MATTEW DANIEL, ADỌGBAJALẸ ỌKỌNRIN, A ṢEYI Ṣ'AMỌDUN O.

Tọkantọkan wa la fi ba arakọnrin wa P. St. Matthew Daniel, Akọwe àtàtà ti nfi wura mukọ, ti kotu Ganran nilẹ yi, yọ fun ọmọ ọdun mejilelogoji ti o dà ni *Monday* ọsẹ yi. Aṣeyi ṣamọdun o. A si ki Mrs. rẹ ọmọ kẹhin o gb'ẹgbọn. Ẹ ku àrà.

OYE A YE S'OWO A YE S'ỌMỌ A YE SI AIKU BABA IWA.

Nkan kán ni Ijọra ni *Monday* ọsẹ yi nigbati awọn ẹbi Ọjọra fi ẹni meji joye Ọdọfin ati Aro. Oye a yè sile o. A si ki awọn ẹbi na, papa *Chief* Ọjọra, ẹ ku inawo ọjọ.

LỌWỌ GUNBẸ-GUNBẸ-AYA GBOGBO, OLUWA RERE, GBA WA!

Ihin titakiji kan ni a gbọ ninu ọsẹ yi nipa ti obinrin kan ti o gun ọkọ rẹ lọbẹ lati ogọro-ẹhin titi de apakan ikun ọkọnrin na ni apa Anikantamọ ti a npe ni *Moloney Bridge Street*, lọna Ẹpẹtẹdo ni ijeje; a gbọ pe ohun to mu sababi yi wa ni pe ọkọ na kilọ fun aya rẹ yi ki o maṣe gbe ọmọ jojolo ti o bi fun on lọ ma ṣe palapala lọdọ ọkọnrin kan ti o mbẹ ni adugbo ibiti tọkọ-tava yi ngbe. Ọrọ na di ija, a si sọ pe nigbati o di alẹ ni aya yi gba ẹhin ọkọ rẹ ṣe ni jamba yi wara-wẽré, a ti fi ọpọlọpọ aṣọ we ikun ọkọ na nitori ifun rẹ fẹ bọ sita, kiakia o di ti Dokita Vaughan ni Idunṣagbe. Nigbati aya-eṣubeleke yi ri iwà ti on hu bẹ o f'ẹsẹ fẹ: ṣugbọn ọwọ tẹ nikẹhin o si ti di "iyawo" awọn Ọpa Ọba nisisiyi.

Ni akoko kan ni igboro ilẹ yi a gbọ pe ọdọmọde konrin kan ba aya rẹ ṣe àwọ lakoko kan niwọn oṣu mẹrin sẹhin, nigboro ilẹ yi; eyiti a nwi yi ti pẹ, bẹ ni obinrin na bu ọkọ rẹ jẹ yanna-yanna; iyoku iregbe, aiperi wọ oju awọn ọgbẹ ti aya elehin-oro yi da si ọkọ rẹ lara; ki a ma fà gun lọ titi, nṣe ni ọkọ yi ba ọgbẹ na rin; akọwe ọkan ninu awọn Lọya ilẹ yi ni ọkọ yi nṣe, o si tutu ju omi amu lọ, ọga rẹ gba odidi Dokita meji fun titọju akọwe rẹ; nwọn si ṣe itọju ọmọdekọnrin na depò; ṣugbọn arun l'àwo a ki i wo iku, bayi ni ehin-oro aya ọmọde yi ran lọ s'ọrun ọsan gangan.

Ẹwẹ obinrin kan ṣe ọkọ rẹ lọṣẹ ni Ilu Aganyin ni ọdun diẹ sẹhin nigbati aya yi nba ọkọ rẹ binu pe o nfẹ obinrin miran; nigbati o di oru nkọ ti nwọn jọ dubulẹ pọ̀, aya-apania yi kò rọra yọ kubẹ-kubẹ kuro ni ẹgbẹ ọkọ rẹ nigbati o ti sun lọ fọnfọn—"Peu" lẹsẹkanna lo fi abẹ ifari (*Razor*) ge nkan ọmọkọnrin ọkọ rẹ yi: o dabi ẹnipe obinrin eleṣu yi sọ ninu ọkan rẹ pe kàka ki "Baba Bọyi" na jẹ ti obinrin keji, on a kuku gẽ sọnu, tobẹ ti ko fi ni jẹ t'on tabi ti oni tọhun mọ. Ọwọ ofin ma tẹ aya eleṣu yi nikẹhin, a si fi si ẹwọn ọdun gbọrọ; eyi mu ni ranti adura ti Ọgbẹni kan John Ploughman ni Ilu Oyinbo

nsaba ma ngba pe "*God save us from wives who are Angels in the streets, Saints in Church, BUT DEVILS at home*" eyini ni pe, ki Oluwa ṣọ ni lọwọ aya ti nwọn jẹ Maleka ni ode, ti nwọn jẹ Ẹni-mimọ ni Ṣọṣi, ṣugbọn ti nwọn jẹ EṢU BELEKE nile.

Ẹ KU EWU U U U !!!

A ba Ọgbẹni Abudu Karimu Jẹnmi ti *No. 69, Taiwo Street*, yọ fun jijare ti o jare ẹjọ ti Ọgbẹni Theophilus Johnson pe ni Ganran, pe o wa tilẹkun ile on, o si ko gbogbo nkan on lo ta, lai gbaṣẹ Kotu: ẹjọ na ti wa nilẹ lati oṣu *June*, ọdunni. Adajọ Van der Meulen ṣa ọgbọn pọnun pẹlu ọgbọn ṣile mọ ẹlẹjọ na lara, ni sisan fun owo irin-ẹsẹ, fun ẹniti o pe lẹjọ. Ẹlẹjọ gba Lọya E. Jenkins Harrison, ẹniti o si jẹ'jọ gba Lọya S. H. A. Baptist.

O PARI !

A daro iku Mrs. Luke ti Ẹhin-Ọgba ti o ṣẹlẹ ni alẹ *Thursday* ọsẹ yi: a ki awọn ọmọ ati ẹbi oku gbogbo, Ẹ ku Afẹku.

## GIDIGBO ! GIDIGBO !! HEYA !!!

ẸNI BA LE JA KO JADE.

[ *Lati ọwọ* Ajọjẹ-'o-dun. ]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Ko dede ti mo fi pe ija si oke iwe yi nitori awọn Onirara ni o ma nkọrin tabi ni o ma nki oriki pe—Ọnani-nani Alapata nnani ẹdọ ẹran, bẹ si ni Aṣẹgita nnani epo igi, bẹ lo si yẹ ki awọn Onimimọ nani ẹkọ wọn.

Ni ọjọrọ ọjọ Atalata *Tuesday* ni a ri iwe Ikede ti awọn Ahmadia fi pe gbogbo awọn Imale ilẹ yi ti ile ati ti Oko, ti o ba ṣi wa ninu ẹniti o ni iṣiye-meji si ọrọ Ahammed Maadi (Alai Salatu wa Salam) pe o ti de ni o, tabi ko ti de, tabi o tilẹ ṣi iṣẹ jẹ si bi a ti ngbọ ninu Alkoran ṣiwaju dide rẹ pe ti o ba de yio ma ṣe, pe ki oluwarẹ pade awọn ni Ile Iranti Afari Ogun l'Ẹhingbẹti.

Iwe-ikede yi ko ba mi ni ojiji nitori ogun a gbọtẹlẹ ki ipa arọ, a si dupẹ gidigidi fun Ọgbẹni "*Dr.*" wa ti o wéwè pe ki a tun pe ipe na ni ọna bayi boya ti alẹ ọjọ aisun Malud Nabiyi nyẹn bọ si ojiji fun awọn onigege jonijoni ti on ko ọhẹlẹ ati ma ja ẹnu kiri ilu, nigbati a si ṣe ipeja na ni alẹ ọjọ na nipa aṣẹ Alaga ọjọ na kẹkẹ pa ohun mọ awoko lẹnu ni fun awọn ti o nkọ iwe alusi na ṣọwọ si awọn Oniwe-irohin, bi ko ba si si alẹ ọjọ yẹn ni a ko ni mọ pe ki iṣe Oniwe-irohin na gan ni o nṣe atako nla-nla yi si awọn ọmọ lẹhin Ojiṣẹ Ọlọrun yi, a fi igbati o fa awọn ti nwọn nfun ... iro yi ti nwọn ko ni iru, ninu ọrọ rẹ lalẹ ọjọ na, o dabi ẹnipe nwọn nṣẹju si i pe jọwọ—maṣe pe ... lọjọ oni nigbati Ọgbẹni Oniwasu na nfi Ida Maa... nge okun ọrọ awọn alaimọkan wẹwẹ ti ... nyanju rẹ lẹyọlẹyọ Ọgbẹni Alaga wa na kan san... si pe on gba fun ẹ de ipo pe ki enia ni mimọ ki ... si mọ ṣiro lawẹlawẹ bayi ti o ba de ọdọ rẹ a ... mọ ni.

Ẹwẹ, ki a to sọ ọrọ wa yoku di ọjọ ti agan ... bẹ, a bẹ ẹnyin baba wa ti o ni Tira ti o tobi ... ki o lọ si Sango ki o lọ haya Kẹtẹkẹtẹ lọdọ ... Megida ki o ba wọn ru Tira wọn na pade ... Alkoran Mimọ kanṣoṣo ti Ọlọrun fi ran A... Mohammed si araiye pe ki o ma fi ta wa ... awa ntọpa rẹ nisisiyi

Ki ẹ tilẹ jẹ ki onitirẹ ṣe, ki ẹ fi ọmọ silẹ ki o ... gbe ile baba rẹ nitori ẹsin, ki ẹ jẹ ki olobi... ọwọ mu Iyawo rẹ dani nitori ẹsin, ki ẹ ma ... ba olorirere, ki ẹ si ye ta ọjọ Alkorani ni ipa ... a ti ri ijẹkujẹ jẹ tabi ati raye gba ọna ẹbun ... aidara, tabi ati raye dori aiye kodo. A bẹ ... pọ ninu awọn enia wa ti o ni mimọ ti o si ... tarata nipa ẹsin ki o ma ṣai yọju ni ọjọ yi, ki ... kuro ninu oju mi ni a ṣe bi ọmọ ti o njiṣẹ yi ... mi ni mo fi pọn dagba; nitorina ko si Kewu ... ti o le mọ ke ki o fi dabi eyi ti mo ti ke, ko ... mimọ kan ti o mọ kọja mi.

Lakotan, a ni lati fi gbolohun kan tabi mej... ta ọ ji iwọ ọrẹ mi, gbiyanju ki o si ma fi eyi ... nitori orukọ Rẹ :—

1. Ohun rere ni lati ma fi ọpẹ fun Oluwa
   Ati lati ma kọrin si Orukọ Rẹ.
   Lati ma fi iṣeun ifẹ rẹ han
   Li owurọ ati otitọ rẹ li alẹ
   Nitori iwọ Oluwa ti o ti mu mi yọ
   Nipa iṣẹ rẹ emi o ma kọrin iyin
   Nitori iṣẹ ọwọ rẹ.

2. Oluwa iṣẹ rẹ ti tobi to!
   Iro inu rẹ jinlẹ gidigidi
   Ope enia ko mọ, bẹni oye
   Eyi ko ye aṣiwere enia
   Nigbati awọn enia buburu ba ru bi ko...
   Ati igbati gbogbo awọn oniṣẹ ẹṣẹ ba ngi...
   Ki wọn ki o le run lailai ni.

Ki Ọlọrun ki o ṣọ wa ni ibi iṣẹ iparun—Amin.

Mo dupẹ lọwọ rẹ Ọgbẹni Oniwe-irohin, ... ojurere aye ti o fun ọrọ mi yi.

Abusi Oluwa ki o ma wa pẹlu iṣẹ ọwọ rẹ ...

*Amin.*

Emi ni ti nyin nitotọ,

AJỌJẸ-'O-DUN.

## EYI ARA ẸNYIN ARA IDDO, Ẹ MA KU EWU ỌJỌ O.

Karikari, ni a ri ọkọnrin kan ti awọn Ọlọpa baba ẹgbẹ Iddo mu fun ẹsun l'ọsẹ to kọja wipe o o ji ọda (*paint*) ṣugbọn lojiji ni o tu gburu bi adiẹ jade lati Ṣabu baba ẹgbẹ, ti o bẹ si odo Ọsa, Iddo ti o si nm'okun bi ẹja (*fish*) ọbọkun lọ si ọna Ọja Ikorodu fun nkan bi wakati kan (*one hour*) ninu odo Ọsa. Mo gbadun ẹ Ojo Wonkoko ati awọn Ọlọpa Iddo ti o ku fun ayan ẹmi ọkunrin aboṣi na ti ẹ gbala nipa gbigbe ọkọ-wete si oju omi lati lọ fi mu ẹran odo yi. A ki nyin ẹnyin ara Iddo, ẹ ku ewu, ati itọju iṣẹ nyin o.

## DẸDẸ NI AIYE NFẸ—IWỌ ỌRẸ.

Ẹsọ di ọwọ nyin o, ẹnyin akọwe kọwura Ọlọkọ (*Railway*) oju irin Iddo (*The Railway Booking Clerks*) ni ọsẹ ti o kọja ni a gburo wipe awọn Ọpa Ọba mu awọn akọwe mẹta ni *Iddo Station* fun ẹsun wipe nwọn wọn ẹru ọfẹ, a ki yio daruko ẹnikẹni wọn, ṣugbọn ti ẹ ba de *Iddo Station* ẹ o ri awọn akọwe titun mirari ni ipo wọn. Iwọ akọwe kọwura titun ẹsọ di ọwọ rẹ maṣe ṣ'oju ānu fun Burọda, Anti tabi Kọsini rẹ ni ẹnu iṣẹ ọjọ rẹ. Ọlọrun na yio yọ awọn akọwe yi ninu ẹjọ na o. *Amin.*

## ỌMỌ OLOKU ABAJA L'ỌRUN

A ki Arabirin wa aya ologbe Orekan Williams ti Ita Balogun, ku aṣẹhinde iku iya rẹ. A si tun ni lati ki Mrs. Dada o ku inawo ọjọ, ẹhin iya agba yio dara. *Amin.*

## KI L' Ẹ NṢE TI Ẹ PỌ BAYI IYAWO L' A NGBE O.

A ki Salamọtu Adumadan, ọpẹlẹngẹ obinrin ninu obinrin fun inawo ọjọ ọsẹ ti o kọja nipa gbigbe iyawo awẹlẹwa kan fun ẹgbọn rẹ ọkọnrin. Iyawo a bi ọkọnrin ati obinrin.

## KI OLUWA FI ỌRAN MỌ BAYI O!

Ni aṣalẹ ọsẹ ti o kọja ni a gburo ariwo kan ni ẹba ọna ẹhinọgba ni a ba de ibẹ lari ọkọnrin kan ti awọn Gende ọkọnrin meji dimu papakiki pẹlu agbárá ẹjẹ ti o nṣan lara rẹ lọ si ti Dokita Vaughan eyiti a gbọ nipa rẹ ni wipe, on ati iyawo rẹ lo ta iporogan ti iyawo rẹ da lada ṣẹjẹ lara ni dede agogo mẹjọ alẹ. Ki Oluwa rere gbawa lọ'vọ obinrin alagbeledi buruku alada sọn agbara ẹjẹ o. Amin! Amin!! Amin!!!

## OLUWA RERE GBA WA LỌWỌ BILISI, ON ALUSI GBOGBO;

Ni aṣalẹ ọjọ Jimọ (*Friday*) ni a ṣe alabapade awọn arugbo kẹjẹ-kẹjẹ ọkọnrin meji ni ẹba ọna *Luke Street*, Ọja Ereko ti wọn nta ohun si ara wọn wipe ọmọ ọkọ ni mi, ọmọ baba pupọ ni o. Keji ni ki lo ṣubu tẹ on mọlẹ yi, ni o ba pe āyā kan ninu Alukurani, ti o si yọ ọwọ ninu agbada ladani ti o wọ ni ọjọ na lati yan Nọfila ni eti baba arugbo ikeji na.

Ẹyin ọrẹ wa ti o nka iwe *Eko-Akete* ẹ wa ri aiye lode, ohun ti a gbọ wipe o fa sababi na wa ni ọrọ ọtun ilu ati ọrọ osi ilu. Ṣugbọn pataki rẹ ni, nipa obinrin kan ti awọn mejeji ndu mọ ara wọn lọwọ. Yepa! Yepa!! Yepa!!! ẹ r i n l o p a e h i n bayi:—ti nyin to bẹ, ti nyin si tun jubẹlọ ng ko ba nyin wi rara, nigba ara la nbu ara baba arugbo kẹjẹ-kẹjẹ. Ṣugbọn o, ẹ dẹ nkanna fun awọn ọdọmọde o. Bi a ba dagba, a o ye ogun jẹ. Aiye re ọrẹ wa.

TẸNI-MASUN-WỌN.

---

## THE NIGERIAN FOOD TAXES.

The following is extracted from the Minutes of the meeting of the Legislative Council of Nigeria held at Lagos on Tuesday the 20th October, 1925, at 10 a.m.

QUESTIONS;

The Hon. the Commercial Member for Lagos asked what amount it was originally estimated, upon their imposition, that the food taxes would produce annually, and what total amount of revenue was derived from them last financial year.

The Hon. the Comptroller of Customs replied; The answer to the first part of the question is £69,000., and to the second, £145,420.

The Hon. the Third Lagos member asked: In consideration of the fact that importations through the "Cold Storage" consist of articles of diet consumed principally, if not wholly, by the well-to-do members of the community (who can conveniently sustain the high cost of living) and yet such importations are placed on the schedule of duty-free articles, to ask that as rice (imported in bags), stock fish, dried fish, dried pepper and such like commodities are all articles of diet consumed principally if not wholly by the poorer classes who can ill afford to sustain any high cost of living, whether Government will be graciously pleased to specially consider the desirability of also placing those latter commodities on the Schedule of duty-free articles?

The Hon the Acting Chief Secretary replied;

The representation of the Hon. Member will receive careful consideration in due course.

The Hon. the Member for Egba Division asked: What revenue is derived annually from duties on dried fish from Porto-Novo passing in transit through Lagos to Abeokuta and the Northern Provinces, and whether it is not possible, considering the healthy condition of our finances, to allow dried fish from Porto-Novo to pass through Lagos duty free?

The Hon. the Comptroller of Customs replied: It is not possible to say what proportion of dried fish from Porto-Novo reaches Abeokuta and the Northern Provinces. The duty collected annually amounts to about £3,250 and the Government is not prepared at present to place such importations on the free list.

The Hon. the Commercial Member for Lagos :

To ask the chief Secretary to Government whether he is aware that in certain townships an income tax is levied upon the African clerical staffs of mercantile firms, and that the clerical staffs of Government departments are exempted from the payment of that tax ; and whether he considers it desirable that this distinction in regard to taxation should be maintained ?

The Hon. the acting Chief Secretary to Government.

The position as stated by the Honourable Member is correct and is in accordance with the law. There is no intention of amending the law.


The West African Soap Co. Limited
APAPA, NIGERIA

*Manufacturers of*

NEPTUNE
PALE SOAP

BUGLE
PALE SOAP

MAGNET
CARBOLIC SOAP

will send Price Lists and terms to merchants upon application to

P.O. Box 522
Lagos
Nigeria

F 303


## LABARI LATI ỌWỌ ATOLUGBOKUN

### "IṢU TUNTUN KI JẸ K'A RI IDI AGBE BI TILẸ BA FẸ TAN EGBODO A DE?"

Inu wa dun pupọ lati ri Ọgbẹni Y. L. Iginla 3, Iginla Lane, Lagos, ni biṣẹ rẹ titun ti awọn Oyinbo John Holt & Co. ni Docemo Street, Ọba Eko, Ọgbẹni yi wa fun awọn Oyinbo Heycock Alli Street ri, ṣugbọn Ṣabu to tun bọ si yi, ye wo ni.

Irohin kan ni pe Ọgbẹni kan ti orukọ rẹ Atiku ara Isalẹ Eko, wa igbojẹ rẹ lọ lọdọ awọn alawo ni ijọ *Sunday 18th instant* nigbati ọkọ awọn ti wọn de Idumagbo nibiti Ọpa ko bale, ti o wọ lọ ba awọn alawo dojude, o wa nwẹ Oyinbo dure lọ ba, ati ọkọ Saaka alawo, were wọn ti gba, wọn ko jẹki Atiku joye agodongbo; mu ku. Atiku o ku orire. Odidẹ ku soko ifẹ jẹ.

### 1 "IYAWO DUN LỌSIGIN, ỌKỌ TUN MI GBE"

Irohin kan ni lati Ijẹbu Ode pe Ọgbẹni Ayọola Olusọga ẹniti o npogun nile ogun Dokita nilẹ yi, gbeyawo ni Ijẹbu Ode ni ọjọ Thursday ijọ kẹdogun oṣu yi. Oluwa ko ṣe iyawo ni anfani.

ATOLUGBOKUN

### IROHIN JOS.

Irohin kan ni lati *Jos* nipa Ọgbẹni Thomas Augustus Olusọji Bright ẹniti awọn Ọlọpa Hausa puro mọ pe Ọgbẹni yi ati awọn Lebira awọn onihoho Wara were ọrọ yi ọdọ awọn Ọlọpa, nigbati Oyinbo Ọlọpa wa o ri wipe awọn Ọlọpa yi papa lo fi iru nitori pe awọn Ọlọpa yi lo mu Ọti yo ti wọn Ago awọn Ọgbẹni na ti wọn si bẹrẹ si lu, nigbati Ọgbẹni Bright ri iṣẹ ti awọn Ọlọpa ṣe, o fi ẹjọ awọn Ọlọpa sun Oyinbo tirẹ, wa di ile ẹjọ, nigbati wọn de ọhun, Adajọ Ọgbẹni Thomas Bright ko jẹbi rara, o ni ko On a mọ on ti on ma ṣe pelu awọn Ọlọpa yi.

A ki Ọgbẹni Bright o ku ori re.

ỌKỌNRIN ATIPO

GUARANTEED

THE RALEIGH

FOR EVER



# RALEIGH

## THE ALL-STEEL BICYCLE

## MILLER BROS. (L'pool) LTD., LAGOS.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, OCTOBER 24, 1925.

Ẹbẹ l'awa ma mû bẹ,
Ọba toto, darij'Eṣugbayi,
Ẹbẹ l'awa ma mu bẹ,
Ọba toto, darij'Eṣugbayi.
K'o ba le bọ wa 'tosi, wa 'tosi, o,
Ki'nu Eko dun k'alẹ,
K'o ba le bọ wa 'tosi, wa 'tosi, o,
Ki'nu Eko dun k'alẹ,
Ẹ ba jọwọ,
Ẹbẹ l'awa ma mu bẹ,
Ọba toto, darij'Eṣugbayi.

Imale sọrọ ojo kun, o ni, Tõ, Mọ-dala, Ọlọrun jẹri on. Kodede ti a fi sọ bayi, nitoripe ọrọ Ẹbẹ ti a fi ṣe ọrọ pataki ninu *Eko Akete* ti ọsẹ to kọja, ba ọrọ ti ọkọwe CHALLENOR sọ sinu Iwe-irohin *Nigerian Spectator* ti ọsẹ to kọja mu bakanna. Ko ha han gedegbe fun ẹnyin ara wa, pe ẹgiręgi ni ọrọ ọlọgbọn ri si ara wọn, bi ẹni so ogoji m'ọgọjọ, ati pe ti aṣiwere nikan lo nyatọ? Ki a ma tan ara wa jẹ, ki a ma tan ara wa danu, ifẹ ti Ilu ni si *Prince* Eṣugbayi kuro ni ifẹ-ètẹ, o kuro ni ifẹ-yẹpẹrẹ, o kuro ni ifẹ ọrẹ-da bẹnyan 'kọ, o kuro ni ifẹ ari're-ba-ni-jẹ, agbọn-isalẹ, bõ ku larọ, a ya lalẹ.

Ẹnyin enia wa ko si tun ti ibi iṣana kiyesi s'ogun; ki a fi agbara Ijọba mu ẹnikan pataki bi olori ilu, kuro ni'le ati ọna rẹ, ki a si ri awọn Abanidaro, awọn Agbọrandun-bi-iya-kosi, ti nwọn ti na kasikan owo fun ṣiṣajo ki ọran oluwarẹ na le yanju, laijẹpe ẹniti a nṣayan ọran rẹ yi ni kọbọ aiyelujara kanṣoṣo ninu owo ti nwọn nna na, gẹgẹbi awọn Ato-ba-jẹun nileyi ti ṣe fun ọran *Prince* Eṣugbayi, ẹ ko mọ pe nkan-ribiribi ni irufẹ iwa bẹ? Ki ọran ma si ti lori tabi ni'di bi ejo-Ọṣun ki awọn Bọkinni-ti a ti nperi yi si pinnu lati gbe ọrọ na lọ si Kotu Ọba King nibiti ilẹ tẹju ni ilu Oyinbo, ti o le na awọn Sanmari na ni wabiwọsi owo ṣile: ẹ ko ṣai mọ pe irufẹ ifẹ bẹ ti Ilu ni si *Prince* Eṣugbayi kuro ni yẹyẹ? O kuro ni ifẹ k'aroju-ẹni, k'a k... k'o dara, k'a dẹhin ẹni k'a ko yẹyẹ-balẹ.

Irufẹ ifẹ bayi iba le wa larin gbo... Kiriyo, Musulumi ati Abọriṣa ti mbẹ ni... nkọ o, ki ohun ti o ndun Akinpẹlu jẹ ohun ti o ndun Ajayi, ki ohun to si ndun Ay... si jẹ ọran-ẹdun Duro-orikẹ, bawo ni ... ti dun to!

Ni tiwa, a ko b'omi s'ẹnu sọ pe ... ẸBẸ lo le yanju ọrọ yi nigbẹhingbẹh... ẹnyin na ko gburo ohun ti a ni o ṣelẹ l... yi nigbati a sọpe Ijọba fesi si ọrọ-ib... Dokita Jones nipa ọrọ *Prince* Eṣugb... gẹgẹbi Ijọba ti wipe ọrọ na ti kọja, ati ... Ọga awọn Gomina ni'lu Ọba lọwọ-lẹsẹ n... ohun ti Ijọba ileyi ṣe eyini ni, mi... *Prince* Eṣugbayi kuro ni'lu.

Ẹnyin Aṣaju wa l'ọkọnrin, l'obinrin ... jẹki a tun ẹru ọrọ yi di: okun-bata t... ni, o di iṣẹ ikalẹ.

Ẹ jẹ ki a wa ọna bi a o ti ṣe bẹbẹ ki Ijọ... le mu *Prince* Eṣugbayi bọ wa si tosi wa... ko ni si Iga Idunganran o, nitori oju-m... ko yẹ'ri: ọna mẹta ko yẹ ọja: ṣugbọn ki... kuku sowọpọ-bẹbẹ ki Ijọba KING le ... olufẹ-ilu na wa si etile fun gbigbadun ... aiye rẹ toku—a ko ni kò gbadun ni ... awọn Alagbara fi sọjọ si nisisiyi o: ajo ... le dun titi, ki odiderẹ gbagbe ile bi? K... ma ri! Ka ma ri!! ọrọ tian-tian leyi, o... fẹ fifi-lakaye si: ki a bẹbẹ, ki i ṣe tita-ka... rangbọn si Ijọba rara, ki a bẹbẹ, ki i ... didi tẹmbẹlẹkun si awọn Ako-nijẹ wa, b... ki i ṣe ohun ôwọ: ẹnyin na ko ri pe nigb... awọn Aganyin bẹrẹ si i bẹ Ijọba Gẹsi ... ọdun jọjọ, pe ki a le mu Ọba ... PREMPREM bọwa'le fun wọn, Ọlọ... gba ajo, tabi Ọlọrun ko gba ajo? Ọlọ... gba ajo mọnna: nitori bi a ti nkọwe ... PREMPREM ti bọ wa'le sọdọ awọn e... rẹ, a tilẹ fun ni ipo ni Ajọ Igbimọ Mu... siba wọn: Ijọba ibẹ tilẹ nkọ'le gbakan-ṣu... fun nisisiyi; ninu ẹnyin ọkawe wa le ra... pe, ẹ ri aworan kan ti o jẹ mọ ohun ti a ... yi, ninu Iwe-irohin *West Africa* ti oṣu d... sẹhin, nigbati a ya aworan didi-palẹ ile ... ninu iwe-irohin yi ti t'Oyinbo t'Enia D... si nduna wiwo iran ile na: ẹṣẹ ti Ijọba wa ...

pe *Prince* Eşugbayi şe ha to idamẹdọgbọn ẹşẹ ti a sọpe PREMPREM Ọba Asa-nte na ṣẹ, ti a fi wipe tilẹ o gba tasi ija si Ọba KING, ti o fi di ogun wiwà lọ tun iwọn ọdun mejidilọgbọn gbako?

Bi a si ti ri ọrọ yi si leyi: o yẹ ki a mã wo ilẹ, k'a ma w'ẹnu-ọkọ.

Iba f'ẹnyin Aşelu o. Iba!!!

## IPADE ẸGBẸ TUN'LUŞE.

### YIO DARA NI!

[*Lati ọwọ* KEKERE ILU.]

Si Oniwe-Irohin *Eko Akete.*

Iba Ilu o!

Iwe ikede Ipade Ẹgbẹ "Dẹmọ" ti a ri l'ode lọsẹ to kọja je iwe ti a ti nfoju s'ọna rẹ lati ọjọ gbọro. A ni tanma lati fi osẹ yi fun ọrọ Ẹgbẹ Ilu yi ki Oluwa le şe ni olu Ẹgbẹ k'alẹ; şugbọn aitete gburo to jẹ ki o dabi ẹni fẹrẹ pẹ lẹhin ki a to sọrọ nşe ọkan wa kalo-kalo ki ipade ma ti bẹrẹ ki iwe wa to jade.

Laisi ani-ani, Ẹgbẹ "Dẹmọ" ti adape rẹ njẹ "Tunluşe", papin Ẹgbẹ ni l'Eko. Okiki rẹ si tanka ju ti Ẹgbẹ yọ-yo-yọ lọ. Ẹgbẹ Ilu gan ni nigbati a fi idi rẹ kalẹ. Aigburo rẹ nigbogbo igbati Ilu daru jẹ ohun ibanujẹ pupọ nitori o dori Ẹgbẹ kodo. Ko si si nkan meji bikoşe iwa wa l'Ekò—iwa "ẹnyin ẹ şa ma wo mi." A tun sọ lẹkan si pe, ọran ẹdun ni "du" ti Ẹgbẹ nla ti Ilu gbẹkẹle bẹ nwo nigbati idamu ati ibanujẹ ba Ilu.

Ki ohunkohun to le ti şe ikọsẹ bi irufẹ eyi ti a nşalaro rẹ yi ma fọ Ẹgbẹ na, ko ma si şe le tun şẹ mọ ni sababi ọrọ wa eni; mo si tọrọ gafara pupọ ki nto gbe ẹnu le e sọ.

Ẹgbẹ. Ki l'a npe l'Ẹgbẹ? Akojọ enia fun işẹ pataki kan, yala fun iranlọwọ ọmọ-ẹgbẹ ni o, yala fun atilẹhin ọmọ-ẹgbẹ ni o, fun ire pataki kan ni o, fun işẹ ilọsiwaju Ilu ni o—Ẹgbẹ wa fun anfani pataki kan ni. Kini Ẹgbẹ "Dẹmọ" wa fun. O wa fun irẹpọ ati isowọpọ ara Eko to fẹran Ilu, fun ire Ilu wa lọna gbogbo.

Njẹ "Dẹmọ" ha duro lori adehun ipalẹ rẹ? A ko le wipe ko duro nitori ko si adehun paraku ni ipalẹ rẹ. Ko si ipalẹ fun u. Kini ipalẹ Ẹgbẹ?

Ipalẹ Ẹgbẹ ni ilana ti a fi nşakoso Ẹgbẹ ti a si fi nşe Ẹgbẹ, t'a fi ntọ Ẹgbẹ s'ọna. Ilana bayi ni a npe ni "Ofin Ẹgbẹ." Fun iru ilana bayi k'o to mulẹ, Igbimọ pataki lo kọ nsọ lu u, lẹhinna gbogbo Ẹgbẹ a gba a yẹwo finifini ki nwọn to f'ọwọ si. Ilana bẹ ko şai wa ninu "Dẹmọ" şugbọn ti a o ba sọ otọ, ko murọ. Iwe ti Ẹgbẹ tẹ ni iwe ofin, tabi ilana ko kọja ninu Ẹgbẹ lọna ti Ẹgbẹ ode isẹnyi ma ngba ofin. Ko si ayẹwo nigbati Ẹgbẹ peju. Ogede awọn Igbimọ ti gbe e wa siwaju Ẹgbẹ ati pe Makọli mọdi rẹ, o ti tan niyẹn. Aişedede ipalẹ Ẹgbẹ lọna yi ko le jẹ ki a sọ paraku pe "Ẹgbẹ" ko şişẹ rẹ; nitori ko si ẹnikẹni ti ko mọ pe bi ko ba wun Baba-Salẹ ipade kan ko le yọju, bẹ kẹ ti ẹnikẹni ba gbori s'oke larin ipade lati sọ pe eyi yi ko tọna loju on, hiho ni a nho bo, oluwarẹ. Tani ha le fi ra rẹ şẹsin l'awujọ. Lọna keji, nigbati ko si pe bi Ọmọ-ẹgbẹ tabi awọn Aşoju l'ẹgbẹ, bi mẹfa ni o, bi mejila ni o, bi jubẹlọ ni o,—niwọn igbati nwọn ko ba l'agbara lati bere fun pipade Ẹgbẹ, ofin Ẹgbẹ ko murọ niyẹn. Ẹgbẹ ko duro lori ẹsẹ ara rẹ, ọrun Baba-Salẹ to jẹ ologiri ni di-da a silẹ lo duro. Nitorina ni Ẹgbẹ ko şe l'ohun nigbati Ilu nrọ, nitori ko wọ loju alakoso rẹ pe ki ẹnikẹni mu alamọri kan wa, tabi pe ki ibere ti ki yio rọrun lati dahun fun itẹlọrun Ilu ma ba jade. Bayi ni Ẹgbẹ "Dẹmọ," Ẹgbẹ Ilu, ko şe fọhun ninu iwọya-ija Ilu. K'Ọlọrun fi mọ bẹ!

Ki l'ao şe o! Ẹyi ti a o şe ni k'a şi lọ si ipade. Ki ipade kun şibaşiba. K'a lọ pẹlu ọkan kan. Fun ire-ilu ati iduro Ẹgbẹ. Nigbati a ba gbọ irohin Igbimọ Aşofin Ilu tan, ki a woye awọn wo lo şişẹ ti a rohin na ninu Igbimọ. Ki a mọ tani ki a dupẹ lọwọ rẹ, lẹhinna ki a wa bere awọn iyoku nkọ? E ti ri? Ki l'o mu nwọn lohun. Ọrọ lo kan ọrọ o. Kodede ti a fi da amọran bẹ niyi. "Iwe Irohin *Eko Ọsọsẹ*" sọ fun wa pe Dokita Jonsi mu ibere to le ni adọta lọ si Igbimọ (*over fifty questions*) şugbọn ko jatọ lori Şingulu tabi Mọ. Njẹ iyẹn ko tẹ akiyesi? Nibo ni ki ti Ilu wa ti nkan ba nlọ bẹ yẹn. Nkan kan dandan lo şa da'ka rẹ ti a ko fi gbọ orukọ wọn. Ohun abere ni.

Ti a ba yanju iyẹn sẹgbẹ kan tan, o tọ ki a wa bere kilo ti ri ti Ọba wa fida bo ti da; kini awọn Aşoju wa mẹtẹta şe lati dubu ọran na, ki l'o ti ri ti ẹhin ti Ọba wa ti di ara Ọyọ apapandodo tan ti a si ti role rẹ lalaiku, ni ibere nipa rẹ şẹşẹ de iwaju Igbimọ Aşofin Ilu? Bi a ba nşi i, ẹ sọ fun wa.

A pọ ti a nkọwe nipa ọrọ Ilu. Ẹni nwa owo nwa a; ẹni nwa orukọ nwa a; ẹni nwa ipo ati ojure nwa; *Kekere Ilu* ko wa nkankan ju ire-ilu lọ. Iroju, alafia ati alubarika ti ẹru t'ọmọ l'o nwa. Iwe ọtẹ ko raye lọdọ rẹ.

Konko ọrọ lo wa kan nisisiyi. Suru pẹlu inu tutu ni a bẹbẹ fun lori ọrọ na.

Ibere mẹta yi lo tọ ki Agbalagba kan fayọ ni ipade Ẹgbẹ Tunluşe ni Satidẹ:—

1. Ipo wo ni awọn Oloye Eleko wa l'oni?
2. Bakanna ni nwọn ma wa tabi—?
3. Atunşe Ẹgbẹ, bawo l'ao ti şe e?

Ti nkan ba lopọ bayi l'ẹgbẹ, Igbimọ kekere to laiya to si ni lakaye l'a ma nfi atunṣe le lọwọ, ki nwọn ro o, k'ogun, ki nwọn wa gbe e wa siwaju Ẹgbẹ. Ẹnikẹni to ba le ṣoju-isaju ko yẹ ninu Igbimọ bẹ.

**Iwoyi ana nkọ kẹ o?**

**Ki a ma ba ri iwoyi ana, a o wa la konko ibi ti ọrọ Eko gbe ti wọ si.**

Mo tun juba Ilu lẹkansi. Mo tọrọ gafara. *Kekere Ilu* ko si ninu imọ pe nitori Gomina kan, tabi Ijọba, tabi awọn kan ni Ilu, korira Ọgbẹni Herberti Makọli, nitorina gbogbo enia ni lati korira rẹ. Ẹkọ bẹ ko si lọna temi. Ọlọrun kọ yẹn. Ṣugbọn nitori ng ko korira Makọli iyẹn ko ni bi Makọli ba ṣiṣe ki ng ma sọ. Iyẹn pẹlu ko nṣe temi. Ẹni to ba fẹran Ilu rẹ ko ni fi rẹ ẹnikẹni bo ti wun ki oluwarẹ to. Ẹni ti o ba si mọ Ọlọrun ko ni ti itori ọrọ Oyinbo tabi t'olowo ṣa ọmọlakeji rẹ ti. Ohun ti o ma ku ni pe ki gbogbo wa fi inu kan ṣe Ilu. Gbangba dẹkun nisisiyi. Makọli po o, po o ṣan. O le jẹ eṣi; o le jẹ mimọmọ ṣe. Ṣugbọn ko si tabibi pe o ṣi i.

1. Bi Clifford ba tu Eleko jẹ, nitori ilu ati Eleko papa, ọwọ ẹrọ ni ko ba fi mu ọna atunṣe.
2. **Nigbati Ọba ti wa ko da wa fun ra rẹ ohun ti o ba da a pọ mọ Ọba Oyinbo ko nṣe ohun ti a le fi ba Ọba Oyinbo ta kangbọn, tabi ma leri.**
3. Bo ti wun ki a gbọn to, ko dara ki a ko ọrọ ọrẹ ati alabaṣe ẹni danu, tabi ki a ma fi ọwọ tutu mu ra ẹni,
4. Nigbati a ba nba Gomina kan ja, ko tọ ki a gbagbe pe ti a ba gbe ọrọ koja ori iwọn a o ṣe awọn ẹlẹgbẹ rẹ to le ni ọkan ati ṣe atilẹhin fun wa.
5. Bi ọrọ ba de'lẹ, ko tọ ki a fọwọ rọ awọn to jẹ pataki igi-lẹhin-ọgba fun ni ti.
6. **Enia kan ko le da Ilu ṣe. Yio fẹ ẹni lẹhin.**

**A gbe Iwọnyi kalẹ fun Ilu ro wo o.**

AKIYESI.

A ti kọ wosika oke tan ki a to gbọ iro Ajọ Igbimọ Iṣofin Ilu (*Legislalive Conncil*) wipe, niba jogi, Ijọba bi gbogbo ibere Dokita Jonsi lori ọrọ Eleko wo, pe awọn ko ni ọrọ miran ju Iwe Ijọba ti nwọn fi yiyọ Eleko ati eyiti nwọn fi fi Ibikunle joye; Sẹkitẹri Agba si ri si gbogbo ohun ti Ijọba ilẹyi ṣe lori ọrọ na; ati ti Ọbanikoro pe awọn ko gba irohin (*report*) wipe nkankan ṣe nkankan pẹlu Oloye na. Ibere nipa Ọbanikoro buru pupọ nitori ibere ọtẹ ni. Ọla ni a nwo ju ninu nkan gbogbo. Aiwo ọla awọn to le Eleko wọ'ko, ti nwọn fi ọna ẹbùrú jẹ Ọba miran kanna ni Aṣoju wa fi ṣe ibere nipa ẹjọ Ọbanikoro. O ṣẹ s'apa l'eni, to ba ṣẹ si itan l'ọla nkọ? Lọna keji, nigbati ... ti awọn Oloye ti wa ṣi wa nlẹ lai yanju ti ... papa wa nwa jamba Oloye miran—a le ma ... iwa rẹ, iyẹn o ni ki a maṣe fi ẹrọ we ọrọ—nibo ... ntãri ọrọ awọn Oloye ti wa si yẹn? Nipa ... Eleko, ṣe igbayi l'arọ? Ijọba ni awọn gba gbogbo ohun ti Birrell-Gray ṣe awọn ni idunnu ati ... si iṣẹ rẹ, iṣẹ ti Ijọba ran a l'o jẹ pe awọn ... ni lati tunba fun aisin Gomina awọn ko si gba ... pe o bu awọn Oloye wa. Eyi ha lodi si ... ti a ke ake-isimi si nijọsi? A ko ti sọ pe Ijọba ... nfi ọran Ilu ṣere? Ẹni ti nwọn ba fi nkan ... lọwọ, ki nṣe ẹniti nwọn nda, ẹniti nwọn ... lọwọ ko jẹ wa larin Eko, nitosi awọn Ọga rẹ, ... da ohunkohun ṣe. O le ṣi nkan miran ṣe l'ọna ... nwọn ko fẹ, ṣugbọn nwọn o ni ṣi idi rẹ ... Ko si oniwe ti ko mọ yẹn, nitorina ni iwa ... atọkun Ilu ṣe su wa loju pupọ. Eyi yio ... ẹnyin Ilu lọwọ lati tun ilẹ Ẹgbẹ "Dẹmọ" ... gba dara. Gomina ko jẹ da enia gba si iṣẹ ... ki a ma ṣẹṣẹ ni ṣe ofin, ki o da a ṣe fun ra ... gba imọran Ọga-ile iṣẹ ati ti Sẹkitẹri Agba. ... ọrọ k'ọrọ to ba le t'on ti awọn Igbimọ ... nwọn nyanju rẹ. Ẹgbẹ ni titun ipalẹ rẹ wa ... tun u mọ.

**KEKERE ILU.**

---

***THE EDITOR'S OBSERVATORY.***

**What is this, Mr. News?**

The staggering news in town is to the effect ... Decree *Nisi* was served, yesterday on Mr. Thomas ... Jackson Editor of The *Lagos Weekly Record*, by the ... of The Supreme Court, to show cause why he should ... be committed to prison for Contempt of Court in ... of a certain matter which, it is stated, appeared in the ... or issues of his journal in question on the 19th and the ... September 1925, which, it is said, imputed ulterior ... to the Judges of the Supreme Court, thereby rendering them contemptible in the public eye. **The Order, we ... is made returnable on Thursday next the 29th instant ... dealt with in the Supreme Court.**

**Mr. Bright Honoured.**

**On Saturday last at Kano, Mr. E. Oluyele Bright** ... clerk Manager's Office Ebute-Meta, Nigerian Railway, ... is presently on leave, was entertained at Dinner by the ... Social Healthy Club: the after-dinner speeches ... were made, it is reported, were worthy of the ... the occasion.

---

ỌGBẸNI LAGUDA ENIA-ỌLỌRUN, KU'RỌJU!

A ba Alagba wa, Ọgbẹni Abudu Laguda ti Oju-Oto (*32, Massey Street,*) Baba Ọgbẹni Suuti Laguda, Akọwe Relu ... Ebute Mẹta daro iku ọmọ rẹ wundia, ... ṣẹlẹ lọsẹ yi.

Ki Baba ṣe e, lọmọ ọla.

# SERVICE COMPANY.

## ẸGBẸ AFÒWÒ SINNI.

P. O. Box 169,
Broad Street,
LAGOS.

Ọgbẹni tabi Iyãfin,

A fẹ lati kéde fun gbogbo awọn enia ti nra oniruru tabi orişirişi ọjà tita pe awọn Ẹgbẹ ti a npe ni *The Service Company* le ta ọjàkọjà ti ẹnikẹni ba nfẹ ìà ni owó pọkulọ, ojulowo ọja ni nwọn o si ra fun wọn, ti nwọn o si fi ranşẹ si wọn pẹlu.

Eko ni ilu ti gbogbo enia si gba pe o jẹ amu (ilu) fun ọja tita ati òwo-şişe. A si fẹ sọ, bi ẹniti o ti lọ siwaju ninu òwo-şişe pe, a o tubọ jẹki òre òwo rẹ tubọ lọ siwaju ati ki awọn onibara rẹ si pọ. Gbogbo ọja ti a nta, ti a si fi nşowo ni mbẹ lọwọ wa. Nigbakugba ti o ba si jẹ pe ọja tan lọwọ wa, (eyi kĩ sĩ fi igbagbogbo ri bẹ̃, afi bi oja ba jẹ eyiti a dura lẹkanşoşo) a le ra nibomiran fun nyin ni ilẹ yi ni owo ọpọ̃. A si le ranşẹ fun u ni Ilu Oyinbo pẹlu.

ỌNA TI A NGBA BA ENIA ŞOWO.

Fi owo ati iwe ọja ti o nfẹ ra ranşẹ si wa, ati ɔwo diẹ fun inawo Òtẹ Ọba, ati owo ọkọ̀. Owo ti o ba si şiku, a o şiro rẹ sinu iwe wa fun ọ, tabi ki a fi owo ti o ba şiku na ranşẹ si ọ.

A le fi owo ranşẹ si wa lati Ile ti a nfi Iwe ranşẹ kakiri (*Post Office*), nipa sisọ ọ di owo *Paper* wọnyi :—*Money Orders, Postal Orders, Bank Drafts* tabi *Currency* (bi o ba si jẹ *Currency* ni, ki a *register* rẹ ).

ỌJA IPOLOWO.

A le fi ọja bi iwọn pọun meji, mẹta, tabi marun ranşẹ si awọn ti o ba şeşẹ fẹ bẹrẹ owo-şişe. Iwọnyi yio dabi ọja ipolowo, iru eyiti a ba ro pe o yẹ li a o si fi ranşẹ. Òwo daradara ni ẹniti o ba kọ fi ọja wa şẹwọ yio mã şe. Gbogbo agbara ti o si wa ni ipa wa ni a o sa lati şi awọn ti o ba fẹ ba wa şowo lori.

ỌNA TI A O MA GBA FI ỌJA RANŞẸ.

A o ma fi bi owo ọja ti nlọ soke lọ sodo si ranşẹ gẹgẹbi a ba ti ri iwe ẹnikẹni gba lati *Post Office*, tabi ki o ba tubọ le yá, ki a ma fi waya ranşẹ eyiti a ti san owo esi rẹ tẹlẹ. (*Reply Paid Telegram*). A o si ma fi waya ọfẹ sọ bi owo ọja ti ri, nigbakugba ti a ba nri waya ti a ti san owo esi rẹ şaju gbà.

Bi ẹnikẹni ba si nfẹ lati tẹ ohunkohun nipa işẹ rẹ, inu wa yio dun lati mọ bi iru ohun ti o ba fẹ tẹ na ti ri.

**A sin o!**

THE SERVICE COMPANY.

## IROHIN LATI ODE ONDO.

### LỌWỌ ỌRAN TI A KO MỌWỌ TI A KO MẸSẸ, OLUWA RERE GBA WA.

L'ọsan ọjọ *Saturday* 19 oṣu *September* li a ri lojiji ti gbogbo ilu daru ti awọn Ṣankoṣanko Ọba (*Police*) nju firifiri kakiri, nigbati a si wadi irọkẹkẹ yi a gbọ pe ọmọ F. S. Joaquin akọwe Ajẹlẹ ni o sọnu ti nwọn si nwa a kiri. A bẹrẹ si gbọ orişirişi ihalẹ l'ẹnu nwọn pe eyi ni nwọn ma fi sun Ilu Ondo ni ina ti nwọn si ma wa gbogbo Ijoye Ilu junu ati ede miran ti o buru ti o si banilẹru pupọ tobẹ ti ọkan gbogbo awọn Ijoye ati ara ilu fi pami patapata. Bi Akọwe ti ọmọ rẹ sọnu yi ti lọ sọ fun Chief Lisa ẹniti o jẹ igbakeji Ọba ko duro mu aṣọ ki o to bọ s'ode ti o si ranşẹ pe gbogbo awọn Ijoye Ilu yoku, lẹsẹkẹsẹ gbogbo wọn ti pejọ si Lupọnyin niwaju ile Akọwe na, nwọn ni bi nwọn ko ri iku oju nwọn ko ni kuro ninu òkò; ibiti ọkan gbogbo enia şi wa ninu hilahilo yi ni Ọlọpa kan mu ọmọde ti o sọnu yi wa ti o si wipe on ri i ni ile on, akọwe si bi ọmọde yi lere loju gbogbo enia pe nibo lo ti lọ, o si dahun pe on ju kọkọrọ ile baba on nu nitorina ni on şe salọ, nigbati awọn Ijoye ati gbogbo enia gbọ eyi nwọn mi kanlẹ, nwọn si bẹrẹ si ki ara wọn pe "A yọ ara o, a yọ ara!"

Ni ọjọ keji ni a şẹşẹ wa gbọ pe ki işe ile Ọlọpa ni ọmọde yi sa pamọ si, şugbọn o ti rin jinna to iwọn ibusọ mẹwa si Ondo ni ọna Akurẹ ki ẹniti ngbe *Mail* lọ si Akurẹ li o ba a l'ọna ti o si fi şọwọ sile, nitori (*Mailman*) ti mọ pe a nwa ọmọde yi nile. Gbogbo ara ilu Ondo ko le şai gba irufẹ adura ti o wa l'oke yi nitoripe ni oşu *December* ti o koja ni ọran bi irufẹ eyi şẹlẹ nipa ọmọbinrin Akurẹ kan ti o sọnu bẹ ti a ko si ri i iti di isisiyi ti o si di ẹşẹ ti a ka si Ondo l'ọrun oni; njẹ bi nkan ibi kan ba lọ ba ọmọ akọwe ti a nsọrọ rẹ yi lọna nkọ? Ti o jẹ ọmọde kekere ti o sin nnikan salọ ninu aginju igbo, ko ha tun ni di ijangbọn si Ilu Ondo l'ọrun? Ede ti a ngbọ lẹnu awọn Ọlọpa ti nwa ọmọde na kiri ati ihalẹ wọn ọjọ na fihan gbangba pe bi a ko ri ọmọde yi titi di ọjọ keji Ilu Ondo ko le wa ni alafia. O yani lẹnu pe bi gbogbo irọkẹkẹ wọn yi si ti to a ko gbọ nkankan lati ọdọ Ajẹlẹ Ilu nipa rẹ. A bẹ gbogbo wa ti o wa ni'lu yi ati onile ati alejo pe ki a jumọ ma wa ire ilu yi, nitoripe ibiti a ba gbe njẹ, ti a nmu a ki du ki ibẹ bajẹ. "A yọ ara o!"

### EŞI IBỌN.

A şakiyesi pe şişi enia ta ni ibọn l'ọsan gangan şẹ nwọpọ ni agbegbe wa yi, ati ri to igba mẹta tabi ju bẹ lọ ni Ilu Ondo ninu ọdun yi ti awọn ọdẹ nşi enia ta, ti a si ngbe iru awọn enia bẹ wa sọdọ Ajẹlẹ, bẹni a si ngburo iru bẹ ni Idanre, Ilẹluji, ati ibomiran ni agbegbe wa. Eyiti o kani lara julọ ni ti ọdọmọkunrin kan ti o ... ọgbọn ọdun, ti o lọ ş'ọdẹ l'oko ti ode ... şeşi ta ni ibọn l'ori l'ọsan *Friday* ọjọ ... *August*, ti o di ero ọrun lairotẹlẹ.

A bẹ gbogbo awọn ti nşọdẹ ki nwọn ... sara ki nwọn si ma wọ ohun ọdẹ wọn ... nwọn to yinbọ. A si ro pe o yẹ ti awọn ... ati Alaşẹ Ijọba iba şe ofin pe ẹnikẹni ti o ... şi enia ta, yio ni iya ti o ma jẹ, bi bẹkọ ọpọlọpọ ... ko ni bikita ibọn wọn, iru eşi wọnyi ko si ...

### ETO FUN ATI WA AWỌN ARUFIN ONDO ... O L'AGBARA TO.

Niwọn oşu mẹta sẹhin ni a gbọ pe ọkọn... şa obinrin kan lọgbẹ kitikiti lọna Agbabu ... obinrin na silẹ l'apa-ipatan ti o si salọ ... akoko ti Ajẹlẹ Ondo Captain Richards ati ... lọ si etido (*waterside*) fun işẹ wọn, a ... obinrin yi wa si ọdọ wọn ni Okitipupa, a ... on ati aya rẹ şājo obinrin na pupọ nwọn ... ọgbẹ rẹ. Şugbọn titi di isisiyi ọwọ ko ... ọkọnrin na, a si gbọ pe Ikalẹ ni ọkọnrin ti o ... buburu yi, ati pe o si nlọ si abule oko kabi... dẹruba awọn enia. Ohun ti o ti oju su wa ... a ko ri ami pe awọn ti aşẹ Ijọba wa lọwọ ... gbogbo ipa ti wọn ni lati wa a. O ... nisisiyi ti a ni lati ma mu ogiri si iru ... lati wa enia bẹ ri, nitoripe igi gangan ... mi l'oju ati okere lati nmu kuro, nigbati o ... nisisiy eyi a tun di akọsilẹ pe Ondo şa ẹni... a ko si mọ oluwarẹ, nigbati o si jẹ pe Ondo ... mọwọ ko mẹsẹ ọran yi, Ikalẹ ni ẹniti o şe ... gẹgẹ bi a ti gbọ ọ. Ọpọlọpọ nkan ti o ... iwọnyi lọ nşẹlẹ ni Ilu Oyinbo ati ni ibo... oju ti la dada, şugbọn iyatọ ti o wa nibẹ ... lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa inu ati ti ode ... oluwarẹ s'ode bi ẹni yan jiga ti ara gbogbo ... si ma da şaşa, o jẹ ohun ti o nti awa ọmọ Ondo ... o ni ilaju loju lati ma gbọ pe oni a şa ẹni... ni agbegbe Ondo, ọla a ta ẹnikan n'ibọn, ... ẹnikan sọnu a ko si ri i, bẹni ọwọ ko si tẹ ... ti nşişẹ buburu yi. Nitorina a bẹ awọn ... agbara wa lọwọ rẹ pe o to akoko lati ş'eto ... ọwọ le tete ma tẹ awọn oluşe buburu wọnyi ... ti ri ni ilu miran gbogbo ti nwọn ti ni ilaju.

ẸKIMOGU...

### LABARI LATI ABẸOKUTA

Si Oni 'we-irohin *Eko Akete*

A bẹrẹ foji,

Jọwọ ma şai fun wa ni aye diẹ ninu iwe ... rẹ lati dupẹ lọwọ "Awodi Oke" ti ko mọ pe ... ilẹ nri on, fun ibakẹdun rẹ fun "Ọmọlu... J. Ọla. Majiyagbe "Ohun to şe ki si'le ti o ... ki so de." Eyi şe àrà loju rẹ nitori ero inu ... lati fi "Sanmọri" yi şe "yẹyẹ" şugbọn iba ...

pupọ bi o ba jẹ pe o fi suru wadi ọran na ko to fi ranṣẹ si nyin fun titẹ. "Lọtọ ọpọlọpọ iwe abẹle ni awọn abanijẹ kọ si Alake" nipa "Sanmọri" yi, laiti orukọ si (*anonymous letter*) ti Alake ko kasi gànlẹru rẹ nipa owo (*vote*) ti o wa nibẹ ti a fun ni (£3) pọwun mẹta lọṣọṣu titi a o fi pese fun ninu iwe owo ajọdun (*Estimate*) lọdun 1926, ohun ti o mu pẹ ntuka yi wa niyi, boya eyi le tọ na fun "Awodi Oke ṣugbọn gasikialy *speaking* ko to ra epo Oyinbo (*Petrol & oil*) sinu kẹkẹ mọto (*Harley Davidson Motor Cycle*) ti "Sanmari" yi ngun lọ si ibi iṣẹ. Majiyagbe ti jẹ ete malu ẹran kekere ko ka lẹnu mọ, ko si le fi ehin (*teeth*) Ọga yi ilasa Pọwun mẹta ṣe ohun ajeji.

Lọsẹ to kọja Awodi Oke sọrọ daradara nipa *Concert & Dance* lati ọwọ Majiyagbe ati Mrs. Adefolu fun Ọla Ọba wa Ademọla II. A ko le gbagbe alẹ ijọ na, Ilu Ọba wa tunbọ ndun si nigbati a ri awọn ọmọbinrin wa bi Miss Ilọri olohun didun ati Miss Fisher olohun iyọ ati Ijo (*Ball*) wọn Miss Darley, Wilson, Jones, Oye Adefolu Shọlọtan, Smith, Kuforiji ati awọn miran.. Majiyagbe wulo nibi ere ati nibi iṣẹ iranti idugbolu (*Collision*) Mọto meji ni ikorita Ibarapa (*Ibarapa point*) bi o ti wi ni Adajọ Ṣowande da ni Kotu, o ṣe iranti ijo ti o kọkọ gba Ẹjọro niwaju Adajọ Beckley lọgan o ti pari Ẹjọ bi mẹwa, a fi ọran yi le Igbimọ lọwọ lati ṣe eyiti o ba tọ, Majiyagbe yẹ Ijọba Ẹgba. Ẹ mu gbogbo tẹnbẹlẹkun pe Oyinbo kan korira rẹ lainidi kuro, ohun to wun mi ko wun ẹ, a jẹun lọtọtọ.

AGBỌRANDUN.

Abẹokuta.

---

## IROHIN IJẸBU ODE.

### IROHIN DIẸ LORI ỌGBẸNI S. O. ODUGBẸSAN—OLOGBE.

Ni akoko igbe aiye Ologbe yi, ni ọdun 1910 o lọ si Eko fun ile iwe kekere, o ṣe ile iwe kekere ni abẹ Ẹni-ọwọ D. F. A. Jones nigbati o fi wa ni (*Headmaster*) Ọga ile iwe ni Ebute-ero *Lagos*. Fun bi ọdun meji, nigbati o jade nibẹ fun iwe karun *Std. V* o pada wa si Ijẹbu Ogere fun (*Pupil Teacher*) Tiṣa kekere, labẹ Ọgbẹni E. G. Ṣokalẹ fun bi ọdun kan pere; on pẹlu awọn meji kan bayi lo jọ mura fun ire ije ti aiye yi, orukọ awọn mẹtẹta niyi—Ọgbẹni Samuel Ogunja Odugbẹsan—Ologbe, Ọgbẹni Josiah Matanmi Ọṣimosu ati Josiah Ọlabajọ Oshobọwale awọn meji wa nidi iṣẹ Olodumare nisinsiyi. Lati mura fun ẹkọ ti o ji rere *Training College* Ọyọ ni 1914, o wa labẹ itọju fun bi ọdun mẹta (*three years*) ni Ọyọ. Nwọn jade bi Olukọ pataki. Ọgbẹni S. O. Odugbẹsan yan sori Ijọ Iporogun, Ijẹbu Ode ni ibẹrẹ ọdun 1918 titi o fi de 1921, a si tun ran lọ ṣe Olukọ awọn Obinrin ni *Girls' High School*, Ijẹbu Ode, olupilẹṣẹ iṣẹ ibẹ ni ile Ogunade, Bọkinni, ni wọn jọ pejọ si nigbana; o jẹ alapọn ati oṣiṣẹ totọ o le ṣe ayan pupọ ati ma kọni ni ẹkọ. Ninu ọdun 1921, o ran Iyawo (*Lady*) rẹ lọ si *Girls' High School*, Kudẹti, Ibadan. O si wa gbe ni Iyawo ni *February* ọdun 1923, igbeyawo wọn dun pupọ ti a ko le fẹnu sọ. Lẹhin eyi wọn yan a lọ sori Ijọ Odogbolu lati 1923, ọdun lo ti gbadun aiye rẹ mọ ọ. Ọmọkunrin gba iwe ẹri ipo kini ti Ijọba (*First Class Teacher's Certificate*) ati iwe mẹrin miran ṣugbọn ko gbadun iwe ẹri yi tobẹ laiye rẹ, eyiti o fi gbadun iwe ẹri yi ko ju bi ọdun meji pere (*two years*). Ka ma fa gun lọ titi, arun bi Ẹgbẹkọ si kọlu, o gbe ṣanlẹ bi ọdun kan ati oṣu mẹjọ a si ri pe o lọ jẹ ipe Olodumare.

Ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu *May 1925*, anu si ṣeni lati sọ diẹ nipa ti Iyawo Ologbe yi, fun ifẹ nlanla ti wọn ni si ara wọn ni gba aiye wọn titi wọn pada de ọdọ Olodumare ni oke *Paradise*, bayi ni Iyawo ologbe yi lo pade Ọkọ rẹ ni ọjọ kọkandinlogbọn oṣu *September 1925*.

Iyawo rẹ yi jẹ ọmọ tutu ati ọmọ rere nigba aiye rẹ, o si bi ọmọ ọkunrin kekere kan fun u. Mrs. S. Odugbẹsan ku ni Ogere Ijẹbu Rẹmọ ni dede agogo mejila ọsan *Tuesday* ọsẹ to kọja, a si sin ni irọlẹ ọjọ na pẹlu; Baba rẹ mbẹ titi di isisiyi.

### AIYE RE O.

A wi ma yẹhun ni Baba, ẹniti nfi Ọba aiye jẹ ko ju oṣu mẹrin ti Ọkọ rẹ ku lo fi wọkọ tọ Ọkọ rẹ lọ ni *29th day of September 1925*. Bi nwọn ti gbeyawo laiye bẹ ni nwọn lọ gbeyawo lọrun pẹlu:

O dun ọpọlọpọ de ọkan fun iku ti o ba lojiji.

### IKAN DE O.

Ni irọlẹ ana 5/10/25, ni Mr. Obilana olori awọn aṣiṣẹ ọna (*The Head Road Overseer*) lọ sọdọ Oyinbo D. O. Ajẹlẹ kekere lo fi ẹjọ Mr. Delọ-Dosunmu aburo Lọya ti o ti wa bi *Section man* owo ti o ngba ko ju pọun kan pẹlu abọ lọ £1. 10. 0. iwọ Obilana ti o ngba bi pọun marun £5. 0. 0. pe o kọruko ẹlomiran mọ awọn to fi nṣiṣẹ ni ọna Ijẹbu Igbo. A o gbọ bi nwọn yio ti ṣe si ni *Tuesday* to mbọ 6/10/25.

Ikore *Catholic Mission* Ijẹbu Ode a ko ti iri iye gbogbo owo ti Ikore ta ṣe lojọ 4 10 25, *Sunday* tan, ẹ ma gbọ lọsẹ to mbọ o.

ỌBA-N'TA.

---

### IPADE DẸMỌ.

Ipade Dẹmọ mbẹ lọsan yi lagogo mẹrin nile Afari-ogun l'Ẹhingbẹti.

## *Preachers for To-morrow.*

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**CATHOLIC.**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yio ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

(Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.
ST. MICHAEL'S) Lafiaji.)
MORNING. 7—8 8.30—9.30
EVENING. 5.45—6.30

**ANGLICAN**

*Time.* *Preacher.*
9 a.m. Christ Church, The Vicar
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. Paul's (Breadfruit) The Archdeacon
6.30 p.m. do. The Curate
9 a.m. St. John's (Aroloya) Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. Peter's (Alapako) Rev. S. V. Latunde
6.30 p.m. do.
9 a.m. Holy Trinity (Ebute-Ero) Rev. W. O. Aiyedun
6.30 p.m. do.
9 a.m. St. David's (Jordan) Rev. J. H. Ogunro
6.30 p.m. do. do.

**WESLEYAN**

10.30 a.m. Tinubu Rev. J. W. Stacey
7 p.m. do. Rev. L. R. Potts-Johnson
10.30 a.m. Ereko Rev. A. N. Cole
3 p.m. Rev. D. A. Tekoe
10.30 a.m. Olowogbowo Rev. E. E. Williams
7 p.m. do. Bro. Adam
10.30 a.m. Ọbun Eko Rev. S. A. Pearce
7 p.m. do Bro. Samuel O. Taiwo
Williams' Memorial Wesleyan (Ebute Mẹta)
10.30 a.m. Rev. D. A. Bababunmi
7 p.m. do. Bro. J. W. Smith

**AFRICAN**

9 a.m. Jehovah Shalom, Bro. Ọlaboye Lalẹyẹ
6.30 p.m. do. Bro. S. U. Jaja
9 a.m. Christ Church (Ebute Mẹta)

5.30 p.m.
9 a.m. Bethel Rev. J. Ṣotayọ Williams
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. Zion Rev. N. J. D. Ṣomuji
6.30 p.m. do. do.
9 a.m Salem Church (Ebute Mẹta)

6.30 p.m. do.
9 a.m. Bethlehem Church (Ebute Mẹta)

6 p.m.

10. a.m. African Methodist Bro. J. A. Oshodi
7 p.m. do. Rev. I. O. Oyekeule

**BAPTIST**

10.30 a.m.
6.30 p.m. Rev. J. R. Williams
9 a.m. Ebenezer Rev. E. C. Alabi
6.30 p.m. do.
9 a.m. Ararọmi Rev. A. A. Puddicombe
6 p.m. do.

**ISHOLARIAN.**

7.30 a.m. Ilupesi Pastor A. Tuakli
7 p.m. Supt. A. Ibaru

**EPISCOPAL**

9 a.m. & 4 p.m. Patriarch J. G. Campbell

**AHMADIA**

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodeinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. [illegible]
(Central Mosque, Arọlọya Street.)

**ZION CONGREGATIONAL**

9 a.m. Kakawa St. Locum Tenens
7 p.m. do. do.

**ARMY**

10 a.m. Glover Memorial Hall
Capt. Jones and the cadets.
7 p.m. do.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m. Opne Air Service at Campbell Square
J. P. A. Taylor

**AFRICAN FAITHIST KOSMON**

5 p.m. 8, Shitta Street. Bro. A. Gbogboade
Ironupiwada (Ebute-Awo)
10.30. a.m. Pastor J. A. Agbeniyi
6.30. p.m. do. do.

---

## IGBẸ L'OWO WÀ.

### EKO.

Bi ọ̀wọ̀ Ekurọ, Epo ati *Cocoa* ti ku ọsẹ yi leyi :—

EKURỌ
£14 15 0 fun *ton* kan
EPO.
£25 10 0—£26 fun *ton* kan
COCOA.
£28—£30 fun *ton* kan.

### AGEGE.

COCOA.
£30—£33 fun *ton* kan.

"O di ọdun marundi-logoji nisinsinyi ti a ti bẹrẹ si ṣe *Mentholatum*, a si mọ ọ kakiri gbogbo aiye bi egbogi ti o wulo fun wiwo:—Otutu orișiriși, Ọna-ọfun ti o ndun-ni, Ori-fifọ, Arun Awọ-ori, ati gbogbo Arun Awọ-ara."




A HEALING CREAM

**Mentholatum**

Mentholatum has been manufactured for 35 years and is known throughout the world as a medicine of great value for Colds, Sore Throat, Headache, Scalp Troubles and all skin ailments.

**THE MENTHOLATUM COMPANY LTD.,**
**SLOUGH, ENGLAND.**

*Over 16 million jars sold last year.*

## J. C. VAUGHAN

Ti ile-ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilekun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna ; bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna.

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atari-Ajanaku lojọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orişirişi Ọkọ ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods ! Superior Quality !! Quick Fortune !!!

---

RICHARD A. AJAYI,

*Fashionable Tailor*

21, Moloney Bridge Street, Lagos.

Come for trial. Fitting Guaranteed

Charges very moderate.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete.*

---

## Saccharine! Saccharine!! Saccharine!!!

*Purer than Sugar, Sweeter than Sugar, Cheaper than Sugar and more economical than Sugar.*

Try it in your Cup of Tea Coaca, Coffee or in your Oats or Paps, you run no risk.

Saccharine is absolutely harmless even to the most delicate system ; it is very good for young and old, it is now in use in many homes "A boon to those who do not take Sugar and to travellers." If you are in doubt consult your physician.

1 Bottle of 600 Tablets for 1/3d.
1 „ „ 500 „ „ 1/-

*Good Bargains.*

Apply to the Manager :—

APALARA STORE,
72, Great Bridge Street,
Ẹnu-owa.

P.O. Box 772,
Lagos, Nigeria.

---

TO LET OR LEASE.

All that piece or parcel of land with the buildings thereon situate at 106, Denton Street, Oyingbo Market, Ebute Mẹta.

Apply to the EDITOR.

---

## Enia Soro Medicine and General Stores.

SHAPON—ITOKU ROAD, ABEOKUTA.

Ẹ o ri ogun Ikọ, Atura ọkunrin ; ogun Ọriu, Igbẹ şoro, Inukikun, ti obinrin ko ba ri nkan osu rẹ ; Aitete loyun, Ewo, Apeta, Igbẹ ẹjẹ, Atọsi, Ẹda, ati orişirişi arun ti nba obinrin ati ọkunrin ja, lọ si ibẹ. Owo pọ̃ ni wọn jasi.

---

ẸNIKEJI,

Aşọ oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3, *St. John Street*, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

**KERE O!**

Ọgbẹni M. Winnet Macaulay, ti Ita Oju-oto l'Eko, *( 32, Vincent Street )* bẹrẹ iṣẹ Ẹrọ Alọgi; Ẹrọ na si ni agbara Ẹṣin mẹfa. Bi idan ni Ẹrọ yi fi nlọ Igbado; ẹnikeji o sekọ ni o, o ṣagita ni o, re danwo owo rẹ ko tani lara, ẹ tete mu Agbado nyin tọ lọ.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKẸ Oniṣowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo loriṣiriṣi, Kọkọrọ ( Iṣika ) t'ilẹkun ati t'apoti loriṣiriṣi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda loriṣiriṣi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọṣan, ati Pakun ti Awo-ẹja loriṣiriṣi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-ṣawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ṣọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, ( l'ebute Olowu ) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, ( l'Anikantamọ ) l'Eko.

O nta Iworo ( Golu ) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. Pereira's, Ṣẹtẹolu Compound, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

*P*rices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

**Coffin! Coffin!! Coffin!!!**

With excellent workmanship and finish on sale at Paul I. Samuel's Workshop 40, Campbell Street, Lagos.

PAUL I. SAMUEL,
*Builder & Contractor.*
**Residence and Office 72, Igboṣere Road Lagos.**

*Cable Address:—*
"ỌTAỌROJU" LAGOS.

**KARIMU KỌTUN,**
P.O. Box No. 505.
3, Docemo Street,
Lagos, ( Nigeria. )

**"Indent's House."**

Import of General Lines, and Export of Produce Commission Agencies undertaken, Correspondence Invited.

**Books Worth Reading,**

On various subjects for Schools and Public Examinations.

Excellent Lectures, Essays, Novels, Dramas, etc. for General Readers and Book-Lovers and comprising Works of prominent English Authors.

R.P.A. Cheap Reprints from Thomas Paine, Ingersoll, MacCabe, Gorham, Herbert Spencer, Stuart Mill, Hækel, Bradlaugh, Huxley, Matthew Arnold, &c. Prices from 1d upwards.

Second-hand Books at about half the published prices; New Books at Bargain prices.
School and Office Stationeries.

Call on, or send enquiry to,

THE ORA BOOK SYNDICATE,
33, Ọbun Eko Street
LAGOS.

**KERE O!**

Iya-afin Mrs. Beckley nṣu Akara didun ( *Cake* ) ta nile rẹ, ni 53, Opopo nla, ŏ gbeyawo ni o, rẽ yan tirẹ nibẹ; o sami fun ọmọ ni o, rẽ yan tirẹ nibẹ; o tọrọ ọmọ ni o, re yan tirẹ nibẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo rẹ.

**Mrs. Beckley of No. 53 Broad Street, begs to announce that she has started cake-baking of all kinds; ever ready to serve!**

# A. Kessler,

*THE INDENT HOUSE*

FOR ALL GOODS FOR THE WEST AFRICAN MARKET

7, Labinjo Lane,
Williams Street,
**P.O. Box 459**

---

COME AND TRY ME!

FOR THE CONOISSEUR

**Crystall Beer Per Case**

**33s.**

**Genuine Pilsener Urguell**

Per Case

**39s. 6d.**

*BREWED IN PILSEN.*

AND THE

**Padlock Brand Beer**

*48 FULL-SIZED BOTTLES.*

Only

**40s.**

Ẹniti ko ba wa ẹran rẹ a bi obukọ.

## The "B'yotiri" Mart

B. O. JOSEPH,

*Licensed Auctioneer, Commission and Sal... Agt, Valuer and Appraiser.*

22, Church Street, Lagos, Nigeria.
(Near Carter Bridge).

Undertakes the sale of all kinds of goods ... properties either by private contract or public ... any part of Nigeria.

He is also willing to act as commission agent ... the local firms.

*(Over 21 years' experience in trade.)*

**Cotton, Sundries, Hardware Provisions.**

Prompt rendering of accounts and quick payment. Moderate Charges.

Sales on MONDAYS and THURSDAYS. Commencing 9 a.m.

*Emergency Excepted.*

Patronage is respectfully solicited.

*Telegrams*
"BEN JOSEPH" Lagos.

The Mart and Office,
22, Church Street,
Lagos, Nigeria.

*Residence*
35, Richards Lane,
Lagos, Nigeria.

---

## TO LET OR LEASE.

A very commodious shop suitable for commercial purposes, situate and being No. 21, Bishop Street, Lagos, presently occupied by Messrs. G. B. Ollivant & Co., Ltd. and will be vacated on the ... of October, 1925.

ALSO

A Land at No. 39, Patey Street, Ebute Metta, measuring 25 x 105 feet, suitable for residential purposes.

For particulars apply to—

B. O. JOSEPH,
*Licensed Auctioneer, &c.*

The B'yotiri Mart,
22, Church Street,
(Near Carter Bridge)
Ebute Ero,
or 35, Richards Lane,
Lagos.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.